# IJỌBA KRISTI NI AYÉ

### Sękariah 6:12, 13; 12:9, 10; 14:4-21

### ĘKỌ 428 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "OLUWA yio si jọba lori gbogbo aiye: li ọjọ na ni OLUWA kan yio wà, orukọ rẹ̀ yio si jẹ ọkan" (Sękariah 14:9).**

**Isinmi Ilẹ**

Ọlọrun ti pa aṣẹ kan nigba ti Israẹli di orilẹ-ede ni Palestini pe ni ọdun keje-keje ni ki wọn fun ilẹ ni isinmi. Wọn ko gbọdọ gbin ohun-ọgbin kan, ohun-ọgbin ti o ba si hù tikara rẹ̀ ni ki wọn fi silẹ fun awọn talaka. A pe eyi ni isinmi ilẹ. Ṣugbọn awọn Ọjọ Israẹli kò gbọran si aṣẹ Ọlọrun, nitori naa O fa ọjọ igbekun Juda ni Babiloni gùn di aadọrin ọdun lati san iye ọdun ti wọn fi kọ̀ lati fun ilẹ ni isinmi pada.

Nisisiyii aadọrin ọdun naa ti pé; awọn Ọmọ Israẹli si bẹrẹ si i pada diẹdiẹ sinu Ilẹ Mimọ́, wọn si ti bẹrẹ si i tun Tẹmpili kọ́ Dariusi ni ọba Mẹdia ati Perṣia ti o rọpo awọn ara Babiloni gẹgẹ bi alaṣẹ gbogbo ayé. Sękariah jẹ ọ̀kan ninu awọn wolii ti Ọlọrun rán lati waasu fun awọn Ọmọ Israẹli niwọn bi okoo-le-ni-ẹẹdẹgbẹta ọdun si okoole-ni-ẹẹdẹgbẹta ọdun o din meji (520-518) ṣaaju ibi Kristi.

**Asọtẹlẹ Ọjọ Iwaaju**

Ọlọrun fi ọpọlọpọ iran hàn fun Sękariah nipa ohun ti o n bọ wá ṣẹlẹ. Awọn nnkan ti o sọrọ nipa rẹ̀ ki i ṣe nipa titún Jerusalẹmu kọ́ nigba naa, ṣugbọn wọn a tọka si akoko oore-ọfẹ ti wa yii tabi igba Ologo: Igba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun. Igba gbogbo ni awọn Ju maa n fojusọna pe ki Messiah wọn dé lati gbé ijọba Rẹ̀ kalẹ ki O si sọ Israẹli di orilẹ-ede alagbara ti yoo ṣakoso gbogbo ayé. Wọn nireti nisisiyii pe bi ọpọlọpọ wọn ti n pada si Jerusalẹmu, ti a si ti bẹrẹ si i kọ́ ilu yii, eyi ni lati jẹ́ akoko ijọba Messia ni ayé.

O dabi ẹni pe nigba gbogbo ni Israẹli maa n jiya, Sękariah si ṣe laye ohun ti o jẹ ki o ri bẹẹ: wọn ti kọ̀ lati gbọran si aṣẹ Ọlọrun. O wi bayi fun wọn: "Dá idajọ otitọ, ki ẹ si ṣe ãnu ati iyọ́nu olukuluku si arakunrin rẹ̀. Má si ṣe ni opó lara, tabi alainibaba, alejo, tabi talakà; ki ẹnikẹni ninu nyin ki o máṣe gbero ibi li ọkàn si arakunrin rẹ̀" (Sękariah 7:9, 10). Awọn ẹkọ wọnyii dabi ẹkọ ti Jesu kọ́ ni pupọ, ṣugbọn ti awọn eniyan kuna lati pamọ. Bi awọn Ju ba jiya nitori aigbọran si awọn ẹkọ wọnyii, dajudaju iya yoo jẹ awọn ti wọn kọ Ihinrere lode oni.

Awọn Ọmọ Israẹli ti kọ̀ lati pa ofin Ọlọrun mọ́, wọn si ti "gún ejika, nwọn si di eti wọn, ki nwọn ki o má bà gbọ́. Ani nwọn ṣe aiya wọn bi okuta adamanti, ki nwọn ki o má ba gbọ́ ofin, ati ọ̀rọ ti OLUWA awọn ọmọ-ogun ti fi ẹmi rẹ̀ rán nipa ọwọ awọn woli iṣãju wá: ibinu nla si de lati ọdọ OLUWA awọn ọmọ-ogun wá. O si ṣe gẹgẹ bi o ti kigbe, ti nwọn kò si fẹ igbọ́; bẽni nwọn kigbe, ti emi kò si fẹ igbọ́, li OLUWA awọn ọmọ-ogun wi. Mo si fi ãja tú wọn ka si si gbogbo orilẹ-ède ti nwọn kò mọ̀. Ilẹ na si idahoro lẹhin wọn, ti ẹnikẹni kò là a kọja tabi ki o pada bọ̀: nwọn si sọ ilẹ ãyò na dahoro." (Sękariah 7:11-14). Sękariah n sọ asọtẹlẹ nipa Ẹmi Ọlọrun pe bi o tilẹ jẹ pe awọn Ju n pada si Jerusalẹmu ni igba naa a o tun tú wọn ká si gbogbo orilẹ-ede, bẹẹ ni ẹnikẹni ki yoo jẹ adun ibukun ti Ọlọrun n tu jade sori Palẹstini nigba ti awọn Ọmọ Israẹli gbọran. Akoko yii de lẹyin ti a kan Jesu mọ́ agbelebu.

**Wọn Kọ Jesu**

Fun ọpọlọpọ ọgọrun ọdun lẹyin ti Sękariah ti sọrọ yii, ni awọn Ju ti kọ̀ lati gbagbọ pe Jesu ni Messia naa ti awọn n reti Rẹ̀, ati Ẹni ti gbogbo awọn wolii majẹmu laelae kọ akọsilẹ nipa Rẹ̀. Jesu wi pe o tọ ki awọn Ju mọ Oun. O wi fun wọn pe ki wọn wo inu Iwe Mimọ ki wọn si wo ohun ti awọn wolii ti kọ nitori pe, "wọnyi si li awọn ti njẹri mi." Ṣugbọn eleyi ko tilẹ mu wọn yi pada. Nigba ti wọṅ kan An mọ́ agbelebu, wọn wi pe; "Ki ẹjẹ rẹ̀ wà li ori wa, ati li ori wọn ọmọ wa." (Matteu 27:25).

Lẹyin ti wọn ba jiya idajọ ti ipọnju Nla, wọn o kigbe pẹlu irobinujẹ nlá nlà fun Messia wọn, wọn o si ri Jesu Ẹni ti wọn kàn mọ́ agbelebu, nigba ti O ba dé pẹlu ẹgbẹgbaarun awọn eniyan mimọ́ lati ṣe idajọ awọn orilẹ-ede ti wọn ti gbogun ti Jerusalẹmu. Wọn o maa wo Ẹni ti wọn ti gún ni ọ̀kọ, "nwọn o si ma ṣọ̀fọ rẹ̀, gẹgẹ bi enia ti nṣọ̀fọ fun ọmọ ọkunrin rẹ̀ kanṣoṣo, nwọn o si wà ni ibanujẹ, bi ẹni ti mbanujẹ fun akọbi rẹ̀" (Sękariah 12:10).

**Agbara Awọn Ju**

Idameji ninu mẹta awọn Ju ni a o pa ni akoko Ipọnju Jakọbu, ṣugbọn awọn Ju ti o kù ni a o gbala nigba ti wọn ba gba Jesu ni Olugbala wọn. Nigba naa yoo jà fun wọn yoo si sọ wọn di alagbara -- wọn o lagbara to bẹẹ ti "ẹniti o ba si ṣe ailera ninu wọn li ọjọ na yio dabi Dafidi; ile Dafidi yio si dabi Ọlọrun, bi angẹli OLUWA niwaju wọn. Yio si ṣe li ọjọ na, emi o wá lati pa gbogbo awọn orilẹ-ède run ti o wá kọjuja si Jerusalẹmu" (Sẹkariah 12:8,9).

**Ọba Awọn Ọba**

Nigba ti gbogbo idajọ ba pari, Jesu yoo gbe ijọba alaafia kalẹ ninu ayé, olu-ilu ijọba Rẹ̀ yoo si wà ni Jerusalẹmu  Yoo jẹ Ọba awọn ọba ati Oluwa awọn Oluwa.  Sẹkariah sọ nipa akoko yii pe: "Kọrin ki o si yọ̀, iwọ ọmọbinrin Sioni: sa wò o, mo de, emi o si gbe ãrin rẹ, ni OLUWA wi. Ọpọlọpọ orilẹ-ède ni yio dapọ̀ mọ OLUWA li ọjọ na, nwọn o si di enia mi, emi o si gbe ãrin rẹ, iwọ o si mọ̀ pe OLUWA awọn ọmọ-ogun li o rán mi si ọ. OLUWA o si jogún Juda ini rẹ̀, ni ilẹ mimọ́, yio si tun yàn Jerusalẹmu" (Sekariah 2:10-12).

Awọn Ju ti o n pada si Jerusalẹmu ni akoko Sẹkariah n fi gbogbo agbara wọn ṣiṣẹ lati kọ́ Tẹmpili, ṣugbọn o wi fun wọn pe nigba ti Messia wọn ba de yoo kọ́ Tẹmpili miiran. "Bayi ni OLUWA awọn ọmọ-ogun sọ wipe,  Wò ọkunrin na ti orukọ rẹ̀ njẹ ẸKA; yio si yọ ẹka lati abẹ rẹ̀ wá, yio si kọ́ tẹmpili OLUWA; on ni yio si rù ogo, yio si joko yio si jọba lori itẹ rẹ̀; on o si jẹ alufa lori itẹ rẹ̀; imọ alafia yio si wà larin awọn mejeji" (Sẹkariah 6:12, 13).

Isaiah pẹlu tọka si Jesu gẹgẹ bi ẸKA, o ni, "Ẽkàn kan yio si jade lati inu kùkute Jesse wá, ẹka kan yio si hù jade lati inu gbongbo rẹ̀: ẹmi OLUWA yio si bà le e ………. ẹmi imọ̀ran ati ibẹ̀ru OLUWA" (Isaiah 11:1, 2).

**A mú Egun Kuro**

Kò i ti si alakoso kan ni ayé yii ti yoo dabi Jesu. Nigba ti O ba jọba, a o mú egun ti o wá sori ayé nigba ti Adamu dẹṣẹ kuro.  Ki yoo si ogun mọ́ ti yoo mu irukerudo ba awọn orilẹ-ède, ki yoo si aisan ati aini ti yoo mu awọn eniyan ni ibinujẹ, ki yoo si èpò ati kokoro buburu lati ba ewebẹ jẹ́.  Yoo ni ọgbọ́n lati yanju gbogbo iṣoro. Yoo fẹran gbogbo eniyan, yoo si mu ki olukuluku eniyan fẹran ẹnikeji rẹ̀ to bẹẹ ti ki yoo fi si ẹni ti yoo dá nikan wà.  Yoo pese ile ati ibi igbadun fun olukuluku.

Fun ọpọlọpọ ọgọrun ọdun ni awọn Ju ti wà ti wọn ko ni ilẹ ti wọn, ṣugbọn Ọlrun ṣeleri fun wọn pe: "Arugbo ọkunrin ati arugbo obinrin yio sa gbe igboro Jerusalẹmu, ati olukuluku ti on ti ọ̀pa li ọwọ rẹ fun ogbó. Igboro ilu yio si kún fun ọmọdekunrin ati ọmọdebinrin, ti n ṣire ni ita wọn" (Sẹkariah 8:4, 5). Njẹ eleyi ko fi apẹẹrẹ alaafia hàn bi?  Ki yoo si ẹni kan ti yoo pa wọn lara, ki yoo si ijọba buburu ti yoo mu ki wọn wà ninu ipayà jamba.  A o ṣe itọju awọn agbalagba daradara, wọn o si layọ, awọn ọmọde ati awọn ọdọ yoo ni itẹlọrun pẹlu ohun ti Oluwa bá pese fun wọn. Oluwa yoo mu gbogbo awọn Ju pada lati gbogbo ilẹ ayé lati maa gbé ni Jerusalẹmu ni igba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun.  "Emi o si mu wọn wá, nwọn o si ma gbe ãrin Jerusalẹmu: nwọn o si jẹ enia mi, emi o si jẹ Ọlọrun wọn, li otitọ ati li ododo"  (Sẹkariah 8:8).

Wọn o ṣe rere pẹlu.  "Nitori irugbin yio gbilẹ: àjara yio so eso rẹ̀, ilẹ yio si hù ọ̀pọlọpọ nkan rẹ̀ jade, awọn ọrun yio si mu iri wọn wá: emi o si mu ki awọn iyokù enia yi ni gbogbo nkan wọnyi" (Sẹkariah 8:12).

**A Ko i ti Muṣẹ**

O lé ni ọgọrun ọkẹ awọn Ju ti o ti pada si Palẹstini, asia wọn si n fẹ́ lẹlẹ lori ilẹ wọn lonii, ṣugbọn akoko ti Sẹkariah sọ nipa rẹ̀ ko i ti dé.  Jesu ko i ti gbé laaarin wọn nisisiyii, o si daju pe ko i ti si alaafia fun wọn nisisiyii. Ni ihà gbogbo ni awọn ọta wọn duro lati kó wahala bá wọn, bẹẹ ni inira pupọ wa fun wọn ni ilẹ wọn nitori ọpọlọpọ wọn ni o pada si ile laaarin akoko ti o kuru to bẹẹ ti wọn ko si mu ohunkohun wá ti wọn le lò fun itọju ara wọn. Leke gbogbo rẹ̀, awọn ara Palẹstini kò sin Jesu.  Awọn wọnyii ko le jẹ́ "iyoku" ti a o gbala ni opin Ipọnju Nla.

**Iṣẹlẹ Nla**

Ni ọjọ nì, nigba ti Jesu ba de pẹlu awọn eniyan mimọ Rẹ̀ lati gbe ijọba Rẹ̀ kalẹ ni ayé, ẹsẹ Rẹ̀ yoo sinmi lori Oke Olifi, ni tosi Jerusalẹmu, iṣẹlẹ nla yoo si wà. Ilẹ yoo sán, yoo si pin oke naa si ọna meji, pẹlu afonifoji nla kan ni agbedemeji. Awọn eniyan ti igba Majẹmu Laelae fẹrẹ má ti i gbọ́ nipa iṣẹlẹ kan ri, ṣugbọn ọ̀kan ti o tobi lọpọlọpọ ṣẹlẹ ni akoko Ussiah, Sẹkariah si sọtẹlẹ pe eyi ti yoo ṣẹlẹ nigba ti Jesu ba de yoo mi ilẹ bẹẹ gẹgẹ: yoo pọ to bẹẹ gẹẹ ti awọn eniyan yoo salọ sori awọn oke fun aabo.

**Omi Iye**

Omi iye nipa ti ẹmi yoo ṣàn jade lati Jerusalẹmu. Nigba pupọ ni Jesu maa n sọ nipa Ẹmi Ọlọrun gẹgẹ bi omi. O wi fun obinrin ti o wà ni eti kanga Samaria bayii: "Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba mu ninu omi ti emi o fi fun, orùngbẹ ki yio gbẹ ẹ mọ́ lai; ṣugbọn omi ti emi o fifun u yio di kanga omi ninu rẹ̀, ti yio ma sun si iye ainipẹkun" (Johannu 4:14). Lọjọ ikẹyin ti i ṣe ọjọ nla ajọ, ki a to kan Jesu mọ́ agbelebu, O kigbe soke pe: "Bi òrùngbẹ ba ngbẹ ẹnikẹni, ki o tọ mi wá, ki o si mu. Ẹnikẹni ti o ba gbà mi gbọ́, gẹbẹ bi iwe-mimọ́ ti wi, lati inu rẹ̀ ni odò omi ìye yio ti ma ṣàn jade wá. (Ṣugbọn o sọ eyi niti Ẹmi ti awọn ti o gbà a gbọ́ mbọ̀wá gbà: nitoriti a kò ti ifi Ẹmi Mimọ́ funni" (Johannu 7:37-39). Nigba ti Jesu bá jọba ni ayé, "aiye yio kún fun imọ ogo OLUWA, bi omi ti bò okun" (Habakkuku 2:14). Jesu ni aṣẹ gbogbo ayé yoo wà ni ikawọ Rẹ̀; yoo si jọba ni ododo ati aiṣègbè. Gbogbo eniyan nibi gbogbo yoo jade wá si Jerusalẹmu lati sin. "Li ọjọ wọnni yio ṣẹ, ni ọkunrin mẹwa lati inu gbogbo ède ati orilẹ-ède yio di i mú, ani yio di eti aṣọ ẹniti iṣe Ju mu, wipe, A o ba ọ lọ, nitori awa ti gbọ́ pe, Ọlọrun wà pẹlu rẹ" (Sẹkariah 8:23).

Awọn eniyan yoo wà ti a o bi ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun pẹlu ọkàn ẹ̀ṣẹ; awọn miiran ninu wọn yoo si kọ̀ lati lọ si Jerusalẹmu lọ sin. Ọlọrun sọ pe Oun yoo mu ki ojo dẹkun lati rọ̀ si ilẹ wọn gẹgẹ bi ijiya. Bi wọn ba kọ̀ sibẹ̀, Oun yoo rán ajakalẹ arun si wọn. Yoo jẹ́ dandangbọ̀n fun awọn eniyan lati gbọran si aṣẹ Ọlọrun, nitori Oun ati awọn eniyan mimọ Rẹ̀ yoo ṣe akoso pẹlu ọpa irin. "OLUWA yio si jọba lori gbogbo aiye: li ọjọ na ni OLUWA kan yio wà, orukọ rẹ̀ yio si jẹ ọkan" (Sẹkariah 14:9).

Nigba ti awọn orilẹ-ede ba lọ si Jerusalẹmu lati sin Ọlọrun ati lati pa ajọ Agọ mọ́, yoo dabi ajọ agọ nlá nlà. Gbogbo eniyan ni a o so pọ ṣọkan ninu igbagbọ, wọn o si gbadun awọn nnkan kan naa. Wọn yoo sin Ọlọrun pẹlu ọkàn kan. Awọn ẹṣin paa yoo ru asia: "MIMỌ SI OLUWA." Ki yoo si iyatọ laaarin Ju ati Keferi. Wo iru akoko ologo ju lọ ti o n duro de awọn olooto ti o fẹran lati sin Ọlọrun nisisiyii, ti wọn si n mura silẹ ni gbogbo ọ̀na ti o ṣe e ṣe lati wà ni imurasilẹ fun bibọ̀ Jesu!

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti Juda fi wà ni oko-ẹrú fun aadọrin ọdun?

2 Ki ni Sẹkariah sọ asọtẹlẹ pupọ ju lọ nipa rẹ̀?

3 Bawo ni awọn Ọmọ Israẹli ti ṣe gba Ihinrere ti Ọlọrun fun wọn?

4 Ki ni yoo mú ki awọn Ju bẹbẹ fun Messia wọn?

5 Bawo ni awọn Ju yoo ṣe ṣọ̀fọ?

6 Bawo ni Jesu yoo ṣe dá awọn Ju lohun nigba ti wọn ba ke pè É?

7 Ta ni yoo ṣe akoso ayé yii ni igba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun? Iru akoko wo ni yoo jẹ́?

8 Awọn wo ni yoo sin Ọlọrun ni igba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun?